# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose kokandinladota: Osu kejila Ojo kerin, 2016**

**Akori oro: Ranti Eleda re…..** Apa kini

**Eko kika: Oniwasu 12: 1-8**

**Afihan**

Ojuse gbogbo eda ise-owo Oluwa ni lati ma ranti Eleda wa, pataki-julo awa ti o wu ninu anu Re ti o fi ore-ofe da ni aworan ara Re.

Opolopo enia ni won gbagbo wipe enikan wa ti o je Eleda ti o da awon sinu aiye, sugbon won ki ranti re tabi ki won fi emi-imore han si. Gbogbo enia ni won nsare ohun ti won yio je, aso ti won yio fi bora, ile ti won yio gbe ati awon ohun amu-yangan ni awujo; nipa bayi won ko ni akoko fun Eleda won tabi ki won ranti Re.

Ere ati di enia pataki ni awujo ni olukuluku nsa kiri, debipe won ri aye fun ohun asan aiye, sugbon won gbagbe Eleda won. Awon enia wonyi dabi "odo ti o gbagbe orisun re, ti yio gbe laisi atunse.

Bibeli wipe " Ranti Eleda re nisisiyi li ojo ewe re, nigbati ojo ibi ko ti ide, ati ti odun ko ti sunmo etile, nigbati iwo o wipe, emi ko ni inudidun ninu won;" **Oniwasu 12: 1.** Awon ewe ko gbodo wipe o di igbati awon ba di arugbo ki awon to ranti Eleda won, nitoripe kosi eniti o mo ohun ti yio sele ni ola tabi ojo-iwaju. Awon arugbo gbodo beresini ranti Eleda won ni kiakia ki iku to de, ki Oluwa ba le fi oju-fo asise ojo-pipe won, ki O si gba won si Ile-Ologo nigbati won ba sun orun-ikehin.

Bi o ba ranti Olorun Eleda re, kise wipe o se ni oore, sugbon o fi eyi mu Oluwa lati gba o la kuro lowo ota ati isoro re, ki o si tun da emi re si ati ki o le pese fun gbogbo aini re. Sugbon awon ti won gbagbe Eleda won, awon ni won nse ara won ni ibi-nla; iru awon enia be ni isoro ati ogun aiye ara won.

Enikeni ti o ba gbagbe Eleda re, ti fi aye sile fun Esu lati je won ni'ya. Iru awon wonyi ko le jogun ijoba Olorun ayafi ti won ba ronupiwada, ti won si ranti Eleda won. O ni lati ranti Olorun nipa sise ife Re ati ase Re, ki o ba le ri ore-nla ati imuse awon ileri Re ninu aiye re.

**Ranti Oluwa Olorun Eleda re**

O ni lati ranti Oluwa Olorun Eleda re, ki o ba le se aseyori ninu gbogbo adawole re, ki o si gbe igbe-aiye alafia. Ni opin irinajo re ninu aiye yi, ao gba o sinu Ile-Ologo.

**Eni mimo Israeli:** Eleda re ti mo wipe ki o ranti kise olorun-ajoji tabi olorun kekeke. On ni eniti nje Alfa ati Omega, nitoripe irinajo wa bere lati odo Re, besini yio si pari si odo Re pelu.

Bibeli pe oruko Re ni “Eni-Mimo ati Eleda Israeli oba wa” **Isaiah 43:15.**

**Eleda Orun on aiye:** Ranti Eleda re, eniti nje:

- **Omi-ni-potenti**: O ni agbara pupopupo, besini gbogbo agbara je tire.
- **Omi-ni-puresenti**: O nbe ni ibi gbogbo labe orun ati ninu orun ni gbogbo igba.
- **Omi-ni-sayenti**: O mo ohun gbogbo, O si le se ohun gbogbo. A kowe re wipe “Iwo ko ti imo? Iwo ko ti gbo pe, Olorun aiyeraye, Oluwa, Eleda gbogbo ipekun aiye, ki isare, beni are ki mu u? ko si awari oye re **Isaiah 40: 28.**

**Olorun ti o da olowo ati mekunnu:** Oluwa Olorun Eleda wa, ni o se’da ohun gbogbo ti o ni emi-alaye ati awon ti ko ni emi-iye, ninu aiye ati ninu orun. On ni o se’da ako ati abo, besini Oluwa ni Eleda oloro ati talaka. Ni afikun Oluwa ni Eleda gbogbo oniruru eya ati enia ti won ni orisirisi awo-ara **Owe 22: 2.**
Bibeli jeri wipe oruko Eleda wa ni nje “Oluwa awon omo ogun” On si ni o da ohun gbogbo, pelu awon irawo, osupa, oorun, ile ati awon orun **Jeremiah 10:16, 51: 19.**

**Olorun ti o njoba titi lai:** Eleda wa joko lori ite-igunwa titi lai, nitoripe ko si eniti o dabi Re ninu aiye ati orun. Oluwa duro lailai, besini okiki ati iranti Re lati iran de iran ni **Orin Dafidi 102:12**.

**Olorun je olore gbogbo enia**: Eyin enia Oluwa, kini awa o san fun Oluwa nitori gbogbo ore Re si wa?. E jeki a ranti lati ma gboran si Oluwa lenu, ki a si ma pa ilana Re mo, nitori gbogbo ire ati iseun-ife Re ninu aiye wa; ki a ma ba ya abara-more-je enia **Orin Dafidi 116: 12**.

**Olorun ko fi aye sile lati ba se orogun:** E mase ya abara-more-je enia bi awon keferi ti won gbagbe Olorun Eleda won, ti won si nhun sin orisa ati awon emi-aimo lati fi mu Oluwa binu. Nitorina, e mase ko iwa awon keferi, sugbon e ranti Eleda yin; ki e si se ife Re **Jeremiah 10:2**.

Mase gbagbe Eleda Re ti o sanu fun o, ti O si gba o kuro lowo isoro ati awon ota re. Fi emi-imore han si Eleda Re, mase wa ninu awon alai-more ti won gbagbe Eleda won ti o fi ohun rere te won lorun, ti o si gba won kuro ninu ajaga ogun ati ide-esu **Orin Dafidi 106:21.**

**Olorun ko gbodo di eni igbagbe tabi ikosile:** Mase gbagbe lati ranti Apata Aiyeraye ti o bi o. Ni gbogbo ojo aiye re ati iwa-laaye re, mase ko Oluwa Olorun Eleda re ti ise Baba ti o bi o sile, ki o ba le dara fun o **Deuteronomi 32: 18**.

## Asiwere enia se iwa-laaye Olorun

Opo enia ninu aiye ko gbagbo ninu iwa-laaye Oluwa Olorun Eleda won. Bi ohun kan ba sele, won yio wipe ise-owo awon eda ti a nfojuri ni, won si le pe isele na je ohun aja-lu. Eyiti o fi yeki won gba wipe Olorun nbe laaye, awon kan ninu won ma nwipe isele na kan se konge ni.

Opo ninu awon onimo-ijinle sayensi fi imo-sokan wipe patiku ni o kolu ara won ti o si da eda-

enia sinu aiye. Imo-sayensi ti a npe ni ariwo-nla (big bang theory) yi ni won si nko awon akeko ni awon ile-iwe ni orile-ede agbaiye. Mo fe ki awon onimo-ijinle sayensi yi mo wipe asiwere ni won.
Satani ti fi iboju bo won loju, o si ti ra won ni iye; lara won ni oro inu iwe-mimo se si wipe "ogbon aiye yi were ni lodo Olorun…." **1 Korinti 3: 19.** Gbogbo ogbon ati imo-ijinle won were ni lodo Olorun, nitoripe, o fi panpe mu awon ologbon ati awon onimo-ijinle sayensi ninu arekereke won.

**Awon asiwere wipe Olorun kosi:** Asiwere ni okan-kokan ti o ba se iwa-laaye Olorun Olodumare Eleda wa. Iru awon enia wonyi yio p'ofo ni aiye yi ati ni aiye ti nbo. Yala won yio jewo iwa-laaye Olorun, ki won si ranti Re, ki won ba le di asegun tabi ki won se iwa-laaye Re, ki won si gbagbe Re, ki won ba le p'ofo. Awon wonyi ni lati mu okan ninu mejeji. Toripe, a ti ko wipe " asiwere wi li okan re pe, Olorun ko si……" **Orin Dafidi 14: 1, 53:1.**

## Awon nkan tabi isele ti o le mu enia gbagbe Eleda re

Orisirisi nkan tabi isele ni o le mu ki enia gbagbe Eleda re, torina, kiyesara.

**Owo ati itura:** Nigbati o ba di olowo, ti itura si deba aiye re, kiyesara ki Satani maba lo ategun oro ti o ni lati muki o gbagbe Eleda Re. Gbo imoran, ewu nbe ni awon akoko ti itura bade ba aiye re.
Nigbati ero-ngba okan re ba wasi imuse, mase jeki o kosi ori tabi opolo re, debipe iwo yio kuna lati ranti Eleda re, ti o ti s'anu fun o **Deuteronomi 8: 13-14.**

**Ani-to ati ani-seku ire**: Mase gbagbe Eleda re nigbati o ba ni ani-to ati ani-seku ire, ti a si fi awon ohun rere te o ni orun. Mase jeki emi-igberaga, emi-ijoraeni-loju, emi-afojudi tabi emi-emini-motoyi muki o kuna lati ranti Eleda re **Hosea 13:6**.

**Ti awon isoro re bati di itan:** Nigbati Olorun Eleda re ba yanju awon isoro aiye re, ti kosi ku wahala kankan ninu aiye re; mase gbagbe Eleda re ti o fun o ni agbara ati ireti, ni awon akoko to s'okunkun ninu aiye re, ti o si fi orin isipaya ati orin ayo si o ni enu **Jobu 35:10**.

**Aluyo ati aseyori:** Nigbati o ba se aseyori ninu gbogbo adawole re, fi ogo fun Olorun, ki o masi se gbagbe Eleda re. Mase fi ogo-aseyori fun ara re, wipe nipa ipa tabi agbara re ni o fi se aseyori. Mase wi ninu okan re pe "agbara mi ati ipa owo mi li o fun mi li oro yi", sugbon ranti Eleda re ti o fun o ni agbara lati ni oro; ki o le fi idi majemu Re ti o bura fun awon baba re kale ninu aiye re **Deuteronomi 8: 17-18**.

**Gbigba riiba, owo-eda ati owo-ele:** Mase gba riiba, tabi fun enia ni riiba. Yera fun itaje-sile ati owo-eda. Sa fun iloni-lowo-gba ati owo-ele pelu awon iwa-eeri gbogbo: bibeko iwo yio gbagbe Eleda re, eyi yio si muki aiye re wa ninu ewu **Esekieli 22:12.**

# Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Adota: Osu Kejila Ojo Kokanla, 2016**

**Akori oro: Ranti Eleda re**…..Apa keji

**Eko kika: Oniwasu 12: 1-8**

Ao tesiwaju ninu eko wa, nigbati ao daruko awon orisirisi ona ti enia le fi ranti Eleda re.

**Awon ona ti o fi le ranti Eleda re**

Opolopo ona ni enia le gba lati fi ranti Eleda re, sugbon die ninu won ni ao menuba.

**Jowo ara re fun Eleda re:** O le ranti Eleda re nipa esin ati ijosin fun un, sin ninu irele, otito ati emi gegebi ese Bibeli ti o wipe "wakati mbo, o si de tan nisisiyi, nigbati awon olusin to'to, yio ma sin Baba li emi ati li otito; nitori iru won ni Baba nwa ki o ma sin on". **Johannu 4: 23**. Nitorina, re ara re sile niwaju Baba re ti mbe ni orun ti ise omo, ti o mo iwo enia ti ise amo, ti o je okan lara awon ise owo Re **Isaiah 64: 8**. Jowo ara re ati aiye re fun Oluwa Olorun Eleda re, ki o ba le dara fun o. Ranti wipe "Olorun ko oju ija si awon agberaga, sugbon o fi ore-ofe fun awon onirele okan" **Jakobu 4: 6**. Tori idi eyi, fi iwa rire-ara-eni sile kun sisin Eleda re ninu otito ati emi; ki ore-ofe aidiyele Re le ma posi ninu aiye re.

**Mase jeki ise Olorun wo'le:** Mase ko ise Eleda re sile, mase pa ise Re ti tabi ki o jeki ise re wo'le. Se ohun gbogbo ti o wa ni ikawo re lati ri wipe o tan Ihin-rere kale, o polongo Ihin-rere, besini o jere okan sinu ijoba Baba re ti nbe ni orun. Nigbati Olorun da Adamu, o fi sinu ogba Edeni lati ma ro o, ati lati ma so o. Idi pataki ti a fi se'da re ni lati se ise Olorun Eleda re, eyi si je okan lara awon ona ti o daraju lati ranti Eleda Re **Genesisi 2: 15**. Ni itara fun ise Olorun, ki Eleda re le mo wipe o ko gbagbe on.

**Baptisimu ati Idapo-mimo:** Ona miran ti o dara lati ranti Eleda re, ni ki o ko'pa ninu Baptisimu ati idapo-mimo. Niwon igbati Baptisimu ati idapo-mimo wa lara awon opo esin-Kristiani, kiko ipa ninu awon ilana yi, yio fi idi re mule wipe o ko gbagbe Eleda re. Eleda re yio ri iwo gegebi eleti-omo ti o gboran si ase on, ni gbogbo igbati o ba nkopa ninu Baptisimu ati idapo-mimo **1 Korinti 11: 24-25**.

**Mase je ologbon ni oju ara re:** Tele awon ilana Eleda re, pa awon ofin Re mo, ki o mase ro ni inu ara re wipe; o ni ogbon tabi imo ju Eleda re lo. Ipokipo ti o le wa ninu aiye, kise nipa ipa tabi agbara re, sugbon nipa ore-ofe Oluwa Olorun Eleda re ni. Nitorina, mase jeki igberaga mu o lero wipe o je olododo tabi o je mimo ju Eleda re lo **Jobu 4: 17**. Bi o ba le'ro wipe o ni ogbon tabi o da ara re loju, kiyesara ki o ma ba subu **1 Korinti 10: 12**.

**Iyin ati Ope:** Bi o ba je okan lara awon enia enia mimo Olorun, o se pataki fun o lati ranti Eleda re nipa orin iyin ati ijo, ni igbakugba ti o ba wa ni iwaju Re. O ye ki o ma fi iyin ati ope fun Eleda Re fun ohun gbogbo ti o ti se ninu aiye re, besini o ko gbodo gbagbe lati fi owo fun oruko Re ti o li ogo. Dupe ni iranti iwa-mimo Re ati ni igbakugba ti a ba nda oruko-mimo Re **Orin Dafidi 30: 4**. Mase gbagbe aka-ainiye nkan ti o ti gbe-se nipase oruko Re, torina ma dupe ni iranti oruko-mimo Re.
Eyin enia mi, e mase jeki a je abara-more-je nipase diduro de akoko ti a ba wa ni ile-ijosin ki a to ma fi ope ati iyin fun Eleda wa. Ni ibikibi ti a ba wa ni abe-orun, aye-kaye ti o ba si sile fun wa, e jeki a lo lati se ajoyo ninu Oluwa Olorun Eleda wa. Fun wipe o da emi wa si lati ri ojo-miran ni ile alaaye, a ni lati dupe ni iranti iwa-mimo Re. Nitorina, e jeki inu awa onigbagbo dun, ki a si dupe ni iranti oruko Re ti o nse ohun iyanu fun wa **Orin Dafidi 97: 12**.

**Fi emi imore han:** Ranti Eleda re nipase kiko orin iyin, ni owuro, ni osan ati ni asale. Mase duro di igbati o ba wa ninu ewu tabi isoro ki o to ko orin iyin si Eleda re. Lehin eyi, ba Eleda re soro ninu aiya re, si jeki emi re ka gbogbo ibukun Re ninu aiye re ni eyo-kokan **Orin Dafidi 77: 6**.

**Fi ibukun fun Oluwa:** Bi o ko ba gbagbe Eleda re, sugbon ti o ranti lati fi ibukun fun On ati oruko Re, Eleda re yio san pada fun o nipa fifi ibukun-aidiyele fun o. Iwe mimo wipe "Fi ibukun fun Oluwa, iwo okan mi, ati gbogbo ohun ti o wa ninu mi, fi ibukun fun oruko Re mimo. Fi ibukun fun Oluwa, iwo okan mi, ma si se gbagbe gbogbo ore Re" **Orin Dafidi 103: 1-2**. Lotito gbogbo ise Eleda re, ni ibi gbogbo ijoba Re ni o gbodo fi ibukun fun un. Awon ohun elemi ati awon ohun ti koni emi, ninu aiye ati ninu orun ni o gbodo fi ibukun fun Oluwa Olorun Eleda won **Orin Dafidi 103: 22**. Nitorina, fi emi-imore han, ki o si yin Eleda re lati inu okan re wa; fun gbogbo anu ati iseun-ife Re si o.

**Ipo-kipo ti o le wa, ma yo ninu Oluwa:** Opolopo enia ni won ma ndun-inu ti won si ma jo-ijo ni igbati a ba pe won si ape-je, sugbon ti won ba wa niwaju

Olorun ni ile-ijosin, won koni jo, besini won yio ma korin bi eniti oku-ku fun. Iru awon enia yi gbodo yipada, ki won ranti Eleda won nipa sise ajoyo niwaju Re, pelu atewo-pipa, ijo-jijo ati iyin lati ara awon ohun-elo orin pelu ilu. O je ojuse re lati se ajoyo ninu Eleda re, ni ojo-isoro tabi ni igba-idera **Orin Dafidi 149: 2-3**.

**Olorun ko ni gbagbe re**

Ao soro nipa awon ohun ti o le se, eyiti koni muki Oluwa Olorun Eleda re gbagbe re.

**Ranti Eleda re nigbati o wa laaye:** Bi o ba ranti Eleda re nigbati o si wa ni alaaye-okan, ti o si se ife Re, nigbana ni koni gbagbe re; sugbon yio ranti re pelu ire-gbogbo ninu aiye. Nitorina, o se pataki ki o ranti Eleda re ki ojo-iku to de, nitoripe kosi ironipiwada ninu isa-oku; fun idi eyi se ohun ti o to, ti o si ye, ki akoko to koja lo, ti ilekun ore-ofe yio si ti **Oniwasu 12: 6-7**.

**Fi ogo fun Eleda re:** Ona miran ti koni jeki Eleda re o gbagbe re ni, ki o ma fi ogo fun ni gbogbo-igba. Igbawo ni o ti ranti lati fi ogo fun Olorun tabi ki o polongo oruko-mimo ati ise-iyanu Re? Niwon igbati o je wipe Olorun da o fun ogo-arare ni, torina, o ni lati fi ogo fun Eleda re ninu gbogbo aseyori ati alu-yo re. Ni igbana ni Eleda re koni gbagbe re **Isaiah 43: 7**.

**Bi enia ba gbagbe re, Eleda re ko ni gbagbe re:** Bi awon enia ba gbagbe re, ti won ko si s'anu fun o nitori ipo ti o wa, Eleda re koni gbagbe re; niwon igbati o bati ranti Re, ti o si se awon ohun ti o se itewogba ni iwaju Re. Lotito yio fi iseun-ife ati anu han fun o, bi o ba le jowo aiye re fun, ti o si se ife Re **Isaiah 49: 15**.

**Bi o ko ba je enia buburu:** Eleda re koni gbagbe re, bi iwo ko ba je enia-buburu tabi onise-ibi, niwon igbati a ti kowe re pe yio pa iranti awon asebi-enia run patapata kuro labe orun. Bi o ko ba feki Olorun gbagbe re, ma se ajoyo niwaju Re, ki o si ma fi iyin fun oruko-mimo Re. Ma fi ope fun nigbagbogbo, ki o si ma fi ibukun fun oruko-iyanu Re. Bikosebe, ao yo oruko re kuro ninu Iwe-iye, besini ao pa re ni ibigbogbo labe orun **Exodus 17: 14**.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kokanleladota: Osu Kejila Ojo Kejidinlogun, 2016**

**Akori oro: Ranti Eleda re**…..Apa keta

**Eko Bibeli: Oniwasu 12: 1-8**

Eko yi yio tesiwaju nipa awon adura ti enia le gba nigbati ogun ba le kankan, ti o si lero wipe Eleda re ti gbagbe re.

**Awon adura ni igba isoro**

Nigbati irobinuje ba gba okan re, ti ohun gbogbo kosi lo dede fun o, sora ki esu maba lo ipo-kotemilorun ti o wa, lati muki o gbagbe Eleda re. Satani ni arekereke, o si le lo ohun ti o nsele si o, gegebi ategun lati tan o je, tabi ki o fi mu o gbagbo wipe Eleda re ko bikita fun o; kosi se dede pelu re tabi oro-aiye re ko ka lara.

Satani yio mu ipinnu yi se nipa gbigbe isoro aiye re ga, ti yio si tembele Eleda re bi enipe agbara kosehunti Re, ko le yanju isoro aiye re. Ranti wipe o di dandan ki o ni igbekele wipe Eleda yio mu oro Re se ati-wipe o ti se ileri wipe "Emi ko je fi o sile, beni emi ko je ko o sile" **Heberu 13: 5**.

Nitorina, ohunkohun ti o ba nla koja, jowo ri daju wipe o ko gbagbe Eleda re ti o ni agbara lati tan wahala re. Ni afikun mase se eke ni majemu Re, tabi ki o re majemu Re koja nitori ipo ti o wa **Orin Dafidi 44:17.**

**Be'be ki a mase ko o:** Jesu Kristi Oluwa ti o ni imo-tele ohun ti yio la koja, soro ni ori igi-agbelebu wipe "Eli, Eli, lama sabaktani? Eyini ni Olorun mi, Olorun mi, ese ti iwo fi ko mi sile?" Bi o ba ba ara re ninu iru ipo-ibanuje yi, be'be ki Eleda re mase ko o sile tabi ki o pa o ti si egbe kan **Matteu 27: 46.**

**Be'be ki a mase gbagbe re:** Mase ba Eleda re wi'jo, sugbon be'be ki o mase gbagbe re tabi pa o ti bi aso-gbigbo. Gbadura ki o mase jeki ota bori re, besini ki o mase ma rin kiri ni igbawe nitori inilara awon ota re **Orin Dafidi 42:9**.

**Idajo**

Idajo Oluwa Olorun yio wa si ori gbogbo okan, awujo ati orile-ede ti o gbagbe Eleda won. Awa onigbagbo ko ni lati kominu, nitoripe awa ko gbagbe Eleda wa, ni idi eyi, ikankan ninu awon idajo ti ao menuba yi ko ni je ipin wa.

**Ao ranti ese awon baba-nla won:** Awon ese baba-nla gbogbo okan ti o gbagbe Eleda won, ni Oluwa yio ranti, ki o le san esan ise won fun awon wonyi. A ki yio pa awon

ese wonyi re, sugbon yio wa niwaju Oluwa nigbagbogbo ki o le ke iranti won kuro lori ile **Orin dafidi 109: 14-15**. Bi o ko ba fe ki Oluwa ranti awon ese baba-nla re, ki o si lo won lati muki oruko re po'ra kuro ninu iranti eda-enia, mase gbagbe Eleda re.

A ko sinu Bibeli wipe oju Oluwa kan si awon ti nse buburu " ninu iwa ati ise won" lati ke iranti won kuro lori ile **Orin Dafidi 34:16**. Beresini ranti Eleda re lati isinsiyi lo, bikosebe, yio yi oju Re lodi si o, yio si pa iranti re re kuro ninu aiye yi.

**Idajo ni aisi itusile:** Awon enia ti o ko Eleda won sile ni lati farabale lati mo oye ohun ti o nbere lowo won tabi ti o fe lati odo won. Won ni lati se ohun ti o to , ti o si se itewogba ni iwaju Re, bikosebe, aiye won yio dojuru ni alaisi eniti yio ran won lowo. A kowe re wipe "Nje ro eyi, eyin ti o gbagbe Olorun, ki emi ki o ma ba fa yin ya pere-pere, ti ko si olugbala" **Orin Dafidi 50:22**. Ronupiwada gbogbo eyin ti o gbagbe Eleda yin, ki ajalu ati iparun to wa si ori yin, ni alaisi eniti yio gba yin.

**Ijiya nla:** Gbogbo okan ti won nwa awon aboku-soro, awon baba-alawo ati awon orisa fun iranlowo dipo eyiti o fi yeki won ranti Oluwa Eleda won, yio jiya lopolopo. Bibeli wipe " Emi o si be ojo Baalimu wo li ara re, ninu eyiti iwo fi turari jona fun won, ti on si fi oruka eti, ati ohun oso re, se ara re loso, ti iwo si to awon ayanfe lehin lo, ti on si gbagbe mi , ni Oluwa wi" **Hosea 2:13.** Mase to awon alafose, awon atuju ati awon onifa lo tabi ki o darapo mo won, sugbon ranti Eleda re ti o da awon enia tabi nkan wonyi ti iwo nwa iranlowo losi odo won. Eleda re ni alagbara-julo, alanu-julo ati olore-ofe-julo, sugbon ki jeki alaigboran lo laijiya.

**Ebo won koni te Olorun lorun:** Opolopo enia lero wipe awon le fun Olorun ni abetele ebun tabi ore, dipo eyiti o fi yeki won se ohun ti o to ni iwaju Re. iru awon enia wonyi ti kuna, nitoripe Eleda won ki ise enia ti a le fun ni abetele layi yi idajo-po, toripe on ni Olorun awon olorun ati Onidajo awon onidajo.

Lakoko, Olorun koni tewogba ebun tabi ore won. Lehin na, yio ranti iwa-buburu won, yio si be ese won wo, besini yio je won ni iya gegebi o se to. Eyi ni yio fi aye gba Satani, lati fi won sinu ajaga-ide ati oko-eru nipa ti emi **Hosea 8:13.** Ranti Eleda re, se ohun ti o to ni iwaju Re, ki ebun tabi ore re ba le se itewogba.

**Ireti won ni ao parun:** Niwon igbati koriko odo kole dagba laini ere, ti esu kosi le dagba lailomi. Nigbati o wa ni tutu, ti a ko ke e lule, o ro danu sin eweko miran gbogbo. Beni ipa ona ati ayanmo gbogbo awon ti o gbagbe Olorun yio segbe **Jobu 8: 11-13**. Bi o ko ba fe ki ipa ona-emi re segbe, bi o ko ba fe ki ojo-iwaju re je alaini-ireti, ranti Eleda re loni ki ireti re ma ba di ofo.

**Awon ere nipa ti ara koni wulo**: Opo enia ni won ti gbagbe Eleda won, ti won si ti

yipada kuro lodo Oluwa Olorun Eleda won, eniti o le gbani-la; besini won ko si nani apata agbara Re ti o nse ibi isadi ati ipamo won. Won gbin ogbin daradara eyiti ise eso-emi sugbon won to ajoji eka eyiti ise ise-ara sinu re. Lotito ni o dagba, sugbon ikore re je okiti-alapa ati bi ohun ti ko si, ti kosi le gbani-la tabi mu itura ba enia, ni ojo ibanuje ati ikanu kikoro **Isaiah 17:10-11.**

Mase gbagbe Eleda re, eniti ise apata oju-agbara re. Ranti ese bibeli ti o wipe "E mase ko iwa awon keferi…." **Jeremiah 10:2** ati wipe "…..enyin ko le sin Olorun pelu mammoni" **Luku 16:13.** Nitorina, e mase da asa ati ise-se yin ti o lodi si eko Bibeli po pelu esin ati ijosin fun Oluwa Eleda yin. Bikosebe, ohun gbogbo ti e ti ni gegebi ere nipa iwa-idapo yi, ki yio le gba yin sile ni ojo iponju tabi ti iku ba de.

**Ekun ati ibanuje:** Gbogbo okan ti won yan ona-wiwo ati ona-ibaje ni aayo, dipo eyiti o fi ye ki won yan ona-ododo, ti won si tun gbagbe Eleda won; yio ni ekun ati idahoro gegebi ipin won **Jeremiah 3:21**. Bi o ko ba fe ki ekun ati idahoro joba ninu ile re tabi ni awujo yin, mase gbagbe Eleda re.

**Won yio di alarinkiri:** "Nitorina, ni emi o tu won ka bi iyangbo ti nkoja lo niwaju afefe aginju. Eyi ni ipin won, apakan osuwon won lowo mi, li Oluwa wi: nitori won ti gbagbe mi, ti won si gbekele eke" **Jeremiah 13: 24-25.**

**Ina yio jo ile won:** Ina  yio jo ile ati ise owo gbogbo okan ti o gbagbe Eleda won, ayafi ti won ba ronupiwada ni kiakia **Hosea 8:14**.

**Ile won yio di ahoro:** Awon enia ti won gbagbe Eleda won, ti subu loju ona won, ni ipa igbani; lati rin ni ipa ti a ko te. Nitorina, ile won yio di ahoro, ati egan lailai; olukuluku eniti o ba koja nibe, yio damu yio si mi ori re si i  **Jeremiah 18:15-16**.

**Won yio jogun orun-apadi:** Ori awon enia buburu ati gbogbo orile-ede ti o gbagbe Olorun li a o da si orun apadi **Orin Dafidi 9: 17**. Bi o ko ba fe lo aiyeraye re ni orun apadi, ranti Eleda re ki akoko to koja lo.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

**Ose Kejileladota: Osu Kejila Ojo Kedogbon, 2016**

**Akori oro: Ranti Eleda re** – Apa kerin

**Eko kika: Oniwasu 12: 1-8**

Abala ti o pari eko yi, ni awon ofin Oluwa Olorun Eleda wa ati awon anfani ti enia le ri nipase riranti Eleda re.

**Awon ofin Oluwa**

Nitori akoko kukuru ti a ni, ao menuba die ninu awon ofin Oluwa ti o diromo iranti Eleda wa.

**Ranti Eleda re ni igbati o si wa laaye:** O je ojuse gbogbo ise owo Oluwa Olorun (yala awon ti o ni emi ati awon ti ko ni emi-alaaye) lati ma ranti Re, papa-julo awa eda-enia ti Eleda ni'fe pupo ti o si gbe isakoso ati ijoba aiye le lowo.
Bi eda-enia ba kuna lati ranti Oluwa Olorun Eleda won, eyi tumo si wipe a nfi apere buburu le'le fun awon eda yoku lati tele. Igbati a ba si wa laaye nikan ni awa eda-enia le ranti Eleda wa. Nitorina, o dara ki a dupe lowo Eleda wa, ki a si fi iyin fun, niwon igbati a si wa laaye. A ni lati beru re, ki a gboran si ase re, besini ki a tele awon ilana re; niwon igbati a si ni ore-ofe.
Bibeli wipe "nitoriti ko si iranti Eleda wa ninu oku: ninu isa oku tani yio dupe fun Olorun?" **Orin Dafidi 6: 5**. Olorun da emi re si fun idi kan ni, ki o le ma ranti re ni igbagbogbo, nitoripe oku ko le ranti re. Nitorina, beresini ranti Eleda re ki akoko to koja lo.

**Fi okan ati gbogbo ipa re fe Eleda re:** Jeki gbogbo ero-ngba re je nipa iranti Eleda re, ki o si fi iranti Oluwa Olorun Eleda re kun okan ati ara re. Jeki ohun ti o wu o julo je oruko Eleda re, besini ki ife-okan re je nipa iranti Eleda re **Isaiah 26: 8**. Fi okan ati gbogbo ipa re fe Eleda re, ki o ba le dara fun o ni ile-alaaye.

**Fi ola ati owo fun Eleda re:** Nibikibi ti o le wa ni abe orun, jeki iwa re, ise re ati oro-enu re bu ola fun Eleda re. Ri daju wipe iwa re ko ta'buku ba Eleda re tabi ki o gan Eleda re, besini mase jeki iwa re fi aye sile fun awon enia lati soro-odi si oruko-ologo Re. Ojuse re ni lati sin Eleda re ninu otito ati emi, o ni lati teriba, ki o si wa lori ikunle tabi idobale ni igbakugba ti o ba wa niwaju Oluwa Olorun Eleda re, lati bu ola fun u. **Orin Dafidi 95: 6**.
Mase ge Eleda re kere ni igba-kankan, sugbon bu iyi fun ninu gbogbo ona re.

Bu ola ati owo fun Eleda re ni ibi-gbogbo. Gbe Eleda re ga, ki o si fi ogo fun oruko re ni iwaju gbogbo awon keferi jakejado agbaiye **Isaiah 17: 7**. Mase se alai-bola tabi alai-bowo fun Eleda re, jeki oju re bowo fun Eni-Mimo Israeli Eleda re.

**Iberu enia:** Niwon igbati o je wipe Olorun Eleda re ni eniti ntu o ninu, mase beru enia ti yio ku, ati omo enia ti a se bi koriko. Ri daju wipe iberu enia ati awon ise won ko jeki o gbagbe Oluwa Eleda re. Iwo ko gbodo wa ni iberu-bojo nigbagbogbo lojojumo nitori irunu awon aninilara re, ti won ti mura lati panirun, toripe irunu na yio dopin lojiji; iwo yio wa, iwo ki yio si ri mo **Isaiah 51: 12-13**. Iberu awon alanu re, ti awon ore re, ti awon aladugbo re, ti oga re tabi eniti o gba o si ise; ko gbodo muki o gbagbe Eleda re.

**Asan-aiye ko gbodo jeki o gbagbe Olorun:** Kiyesara, mase jeki ohun asan-aiye jeki o sako kuro loju ona-otito, bikosebe, iwo yio gbagbe Eleda re ti o gba o lowo awon ota re, ti o si yanju awon isoro aiye re **Deuteronomi 6: 12**.

**O ko gbodo fi talaka se eleya tabi ki o ni l"ara:** Enikeni ti o ba nni talaka lara ti ta'buku ba Eleda re, sugbon enikeni ti o ba se ojurere ati anu fun alaini, ni o bola fun Eleda re, ti o si se ife Re. A kowe re wipe "eniti o ba nni talaka lara o gan Eleda re; sugbon eniti o sanu fun talaka o bu ola fun u" **Owe 14: 31**.
Bakanna, "enikeni ti o ba sin oluponju je, o gan Eleda re: eniti o ba si nyo si wahala ki yio wa li aijiya" **Owe 17: 5**. Nitorina, ranti Eleda re, masi se ni talaka lara tabi sin oluponju je.

**O ko'le fi ara pamo fun Olorun:** Oju Oluwa nlo siwa sehin lori ile aiye. Kosi ohun ti o pamo kuro niwaju Olorun, bi o ba sapamo sinu aja-ile tabi si isale-okun, oju Oluwa ri o. "enikeni le fi ara re pamo ni ibi ikoko, ti emi ki yio ri i" ni Oluwa wi. "Emi ko ha kun orun on aiye?" li Oluwa wi **Jeremiah 23: 24**. Niwon igbati Oluwa nbe ni ibigbogbo ninu orun ati aiye, debipe ko si enikeni ti o le fi ara re pamo ti ki yio ri: se ohun ti o to, nipa riranti Eleda re.

## Awon Anfani

Opolopo anfani ni gbogbo okan ti o ba ranti Eleda won yio ri gba, sugbon ao menuba binti ninu won.

**Ao ko oruko won sinu Iwe Iranti:** Awon anfani ti yio farahan ninu aiye awon ti o ba ranti Eleda won ni iwonyi:

- Olorun yio fetisi ebe ati adura won, yio si fun won ni esi ayo.
- Ao ko oruko won sinu Iwe Iranti **Malaki 3: 16**

**Olorun yio pese fun aini won:** Olorun yio se itoju won gidigidi, yio da abo Re bo won, besini yio tun pese fun gbogbo aini won. Olorun yio da won lohun ni asiko ti won ba nilo iranlowo re, nitoripe on ni oko won **Isaiah 54: 5**.

**Ase oro:** Nigbakugba ti won ba bere ohun kan lodo Oluwa, nwon yio ri i gba, Oluwa yio fi ojo-iwaju han won, besini ase-oro yio ma gbe inu won **Isaiah 45: 11**

**Olorun koni gbagbe won:** Awon ota koni segun won, beni won ko ni ba ijakule pade lori awon adawole won. Ibi ko ni bori won, beni a ki yio yi won nipo pada lailai; sugbon won yio wa ni iranti titi aiye **Orin Dafidi 112: 6**.

**Nwon yio di pataki igun ile:** Ogo Olorun yio bujade ninu iwa-laaye won, beni gbogbo okan ti won ti ro won pin, ni yio teriba niwaju won. Awon ti won ti tembele agbara Olorun ti won nsin, ni ao dojuti ni gbangba. Oro won yio wa di " okuta ti awon omole ko sile, li o di pataki igun ile" **Orin Dafidi 118: 22**.

**Ibukun ni iranti re yio je:** Ibukun ni iranti re yio je, yio si tun je orisun ibukun. Nigbakugba ti awon enia ba ro igbe-aiye re, akitiyan re ati laala pelu iwa-otito re; ayo yio gba okan won, iranti re yio si jasi inu-didun fun won **Owe 10: 7**.

Lakotan, bi o ko ba gbagbe Eleda re, sugbon ti o nranti re lore-kore ni igba iwalaaye re, nigbana ni iwo yio wa lara awon ohun ini-pataki Oluwa. Olorun yio fi o yangan ni gbangba, yio si se afihan re wipe isura-iyebiye ni o. Ni afikun yio dabo bo o, yio si da emi re si; iwo ki yio ni ipin ninu ibinu ati wakati idagiri ti mbo lori aiye **Malaki 3: 17**.

**Edidi: Jobu 11: 16**
Bi o ba pese okan re lati ranti Eleda re, iwo yio gbagbe osi re, iwo o si ranti re bi omi ti o ti san koja lo.